IGBIMỌ ASOFIN ILA ORUN PARI S'ORI RUDURUDU


# IROHIN YORUBA

Ẹgin Oro Wa—"IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"


DỌKITA DOHERTY DI ỌDỌLE IJERO : ARCHDEACON PETERS DI ALAMOJUTO IJỌ BETHEL


VOL. VIII NO. 398 IBADAN, MONDAY MARCH 2 1953 OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)


## Igbimo Asofin Iha Ila Orun Pari S'ori Rudurudu

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹsanlelogun oṣu ti o pari yi ni Ajọ Igbimọ Aṣoju Iha Ila Orun Nigeria (Eastern House of Assembly) mu ipade Ajọ Igbimọ wọn wa si opin lainjẹ ipẹ kan ti o ni iyanju.

Nwọn ti bẹrẹ Ipade Ajọ Igbimọ wọn na to ọsẹ mẹta-abọ lori gbogbo ipade ti awọn ọpọ ni wipe awọn Alamojuto Iṣẹ Ijọba (Regional Ministers) ni awọn ko ni ifi aye iṣẹ na silẹ lasiọpe awọn ri wipe awọn Aṣoju Igbimọ ti o ṣẹwọ nlọ ki awọn fi iṣẹ amojuto awọn silẹ to ilọpo meji awọn ti o afẹ kiwọn sọgibẹ eto ofin Igbimọ.

Ṣugbọn awọn Aṣoju Igbimọ ti o wa lẹgbẹ N.C.N.C. ti iṣe alatako awọn Alamojuto Iṣẹ Ijọba wọnyi sọ wipe awọn ti ju ilọpo meji nwọn lọ ninu awọn ti lati fi aye silẹ ni pẹlu yulasi. Awọn Alamojuto wọnyi ni sọ ṣe ọna ara ni awọn fi dibo ninu ipade Ajọ Igbimọ na ki awọn to o ni ilọpo meji ti nwọn nṣe yi ninu ti awọn ko ba gba fun awọn lati dibo ni ọna ṣọ awọn ko ni fi ara mọ iwa agidi ati jandukọ ti awọn ahọ.

Lori aiḥori alaidi yi ni awọn bẹrẹ eto ofin titun fun ipade Ajọ Igbimọ na patapata gbogbo ofin titun ti ijọba agbe kalẹ fun atunṣe ilu ni awọn Aṣoju Igbimọ ti o jẹ ti N.C.N.C. atako ti awọn ni ayi ijọba l'agbo danu, nigbati ọran na ko ni ajuku mọ ni awọn ba kuku mu ipade Ajọ Igbimọ na wa si opin pe boya ki o to to oṣu mẹta ti nwọn o to tun ni ipade miran awọn ara ilu a ti mọ ọna ti awọn a fi ba wọn yanju rẹ.

## Archdeacon Peters Di Alamojuto Ijo Bethel

EKO—Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu ti o pari yi ni Oni-Ọwọ Biṣọpu A. Abọyade-Cole (Bishop of Lagos) ti Ijọ African Church fi Ẹni-Ọwọ Archdeacon E. O. Peters jẹ oye Alamojuto Ṣọọṣi African Church Cathedral (Bethel) Eko.

Isin Ifijoye Alamojuto Ijọ ti Oni-Ọwọ Biṣọpu Abọyade—Cole fi Alufa na jẹ ni ariarin papọ enia ti pọ nibọ. Ki Olọrun fi ibukun s'ori iṣẹ alamojuto titun na o.



Oba Alaiyeluwa H. C. M. G; C. B. E.
Alake Abeokuta
Ọkan ninu awọn aṣiwaju ọba ninu Igbimọ awọn Oloyè Iwọ-Orun Nigeria.

## ỌLỌLA S. O. AWOKỌYA MU ỌLỌPA

ABẸOKUTA—Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọwa oṣu keji ọdun yi ni Ọlọla S. O. Awokọya (Minister of Education) mu Ọlọpa P. C. J. 1543 fun gbigba ẹẹ̀le meji owo riba lọwọ oni-mọto akero kan. Bi Ọlọla na ti nti irin-ajo bọ lati Ilaro ni ilu Abẹokuta ni o ri mọto na ti o duro. Oni-mọto na ati Ọlọpa na si jumọ duro pọ ti nwọn jọ nsunadura. Ọlọla Awokọya na sọkalẹ ninu mọto rẹ, o si duro bi ẹnipe ko ri eyi ti o kan on pẹlu rọn. Laipẹ ni onimọto na sọrọpọ ju ẹẹ̀le meji silẹ, o si dasilẹ. Ọlọpa na wa bẹrẹ fa tiko lati mu owo na, ara nfu u ninuripe ko mọ ira enia ti Ọlọla na jẹ. Ọlọla na si tọka si owo na, o si bi Ọlọpa na lere pe kini yi! Dipo ki o fi fesi ape ni o ki kẹkẹ (bicycle) rẹ mọlẹ ti o si saa lọ.

Ọlọla na wọ inu mọto rẹ, o si gba lọ, bi nwọn ti de Abẹokuta ni Ọlọpa-inu kan bi Ọlọpa na lere ohun ti o ṣẹlẹ bẹrẹ on yio ti ṣe iranlọwọ fun un, o si ro idi ọrọ na fun un. Ọlọpa-inu na ati awọn enia rere bi mẹfa pẹlu Ọlọla na lati lepa Ọlọpa na nigba-ki Ọlọpa na ri i pe iṣẹ dun ani ni o ba ṣe silẹ lori kẹkẹ ni o ba bẹrẹ igbẹ sibẹsibẹ ọwọ wọn tẹ ẹ, nwọn wa mu fun Olori Ọlọpa (Superintendent of Police). Ọlọla na si sọ fun un bi ọran na ti jẹ.

Ẹ MA A KA IWE
IROHIN YORUBA

## Dokita Doherty Di Oloye Qdole Ijero

IJERO—Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹkẹndinlọgun oṣu ti o kọja yi ni awọn Oloye Afloyejẹ fi Ọlọla Dọkita Akanni Doherty, Oloye Ọkun Eko jẹ Ọdọle Ijero ni Ilu Ijero. Ẹgbẹ enia pataki-pataki nlan ilu na ati lati Eko ni o pe ọjọ̀ lọjọ̀ na, gbogbo awọn Oloye ilu na ati Ọba Ijero paapa pe si ibi oye na pẹlu.

Lẹhin ti nwọn ṣe apakan eto ifijoye na tan ni Ọba Ijero, awọn Ijoye rẹ ati Oloye titun na ati awọn enia pataki-pataki jumọ ya fọto pọ ni Afin Ọba. Nigbati nwọn ya a tan, awọn ogunlọgọ enia tẹle Oloye Akanni Doherty lọ si ilaki o de si, nibẹ si ni nwọn ṣe eto apeyẹ oniṣiriṣi fun ti oye na. Oloye na si fi onjẹ adidun ati oriṣiriṣi ọti tẹ gbogbo awọn alabẹwọọye ọjọ na lọrun, nwọn si nkọ orin awọn ti ajọ. Irohin so to amojuba ni, gbogbo rẹ ndun yungba bi ọsi ala oyin.

Oloye Osẹodi Ijero ati awọn Ọgbẹni D. T. Abraham, A. B. Ajayi ati Iyaafin Grace Fẹmi Dada ba Oloye titun na wa si ile rẹ ni Eko lọjọ na, o si ṣe wọn ni alejo.

## Ipade Igbimo Awon Oloye

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu ti o pari yi ni Ipade Igbimọ awọn Oloye Iwọ-Orun (Western House of Chiefs) bẹrẹ ni gbọngan Apejọ Igbimọ ni Agodi Ibadan, nwọn si pari ipade na ni ọjọ kẹta ti nwọn bẹrẹ. Alakoso Ipade Igbimọ na ni Ọlọla Hugo Frank Marshall, Gomina-Kekere ti Iwọ Orun Nigeria.

Lẹhin ti nwọn ti gba lati fi ara mọ gbogbo eto ofin ti awọn Ajọ Igbimọ Aṣofin Iwọ Orun Nigeria (Western House of Assembly) ti ṣe tan ni Alaiyeluwa Ọba Aladesanmi Keji, Ewi Ado-Ekiti (Ẹniti o ti kọ ẹkọ ni St. Andrew's College Ọyọ) da imọran lati ṣe ofin ti yio mu ki onigbese fi bẹru nipa ki Kọtu Ibilẹ ni agbara lati mu a ta ẹru onigbese (writ of Fi. FA) ti ko ba ri owo san, nwọn si gba ofin na.

Nwọn si faramọ ofin owo-ori ibun (Capitation Tax) pe ti awọn ba bẹrẹ ilo rẹ yio ma anfani papọ wa lori ẹkọ-ọfẹ fun awọn ọmọde ati lati ma a gba ogbegi ati iwọja tọfẹ ninu ilu Iwọsan.

IWE—AMOKUNJALẸ O NI ỌBA AIYE KORI ON, NI ỌBA AIYE KO BA RI I, TỌRUN NRI I.

